# ÌPÈ IHINRERE ATI AWỌN OJUṢE TI O N TẸLE E
## Matteu 11:20-30
## ẸKỌ 82 – FUN AWỌN ỌDỌ

**AKỌSORI: "Ibukun ni fun awọn ti ngbọ́ ọ̀rọ Ọlọrun ti nwọn si pa a mọ́" (Luku 11:28).**

### A Dá Wọn Lẹbi nitori Iṣe Wọn

Bi aanu Ọlọrun ti daju bakan naa ni idajọ Rẹ̀ ri pẹlu. Ọlọrun ti pinnu lati pa awọn wọnni run ti wọn ti rí iṣẹ iyanu Rẹ̀, ti wọn si gbọ́ ọ̀rọ Rẹ̀, ṣugbọn ti wọn kò ronupidwada. "Nitoriti a kò mu idajọ ṣẹ kánkán si iṣẹ buburu, nitorina aiya awọn ọmọ enia mura pãpa lati huwa ibi" (Oniwasu 8:11). Sibẹ, lẹyin ti Jesu kilọ fun wọn, a kò kà nipa isọji nlánlà iru eyi ti o ṣẹlẹ ni Ninefe. Jona kigbe si ilu naa nitori iwa buburu wọn, gẹgẹ bi Ọlọrun ti sọ fun un lati ṣe. Awọn eniyan wá Ọlọrun, wọn si ronupiwada. O ju ọrọ ẹnu lasan lọ, nitori a kà pé Ọlọrun ri iṣẹ wọn, O si dá wọn sí.

Jesu darukọ awọn ilu mẹta nibi ti O ti ṣe iṣẹ iyanu pupọ. O bá awọn ilu wọnyii wí nitori wọn kò ronupiwada, o ju ibawi lasan lọ, O wi pe "Egbé ni fun iwọ." Idajọ Rẹ̀ lori awọn ilu wọnyii gbona to bẹẹ ti a kò mọ ibi ti wọn wa gan an lonii, bi ko ṣe apa kan ni iwọ- oorun Okun Galili.

A kò darukọ Korasini nibomiran mọ́. Bẹtsaida ni ilu Peteru, Anderu ati Filippi. Bawo ni inu wa ti dun to pe awọn eniyan diẹ ni ilu naa gba Jesu gbọ́, wọn ronupiwada a si gba ọkàn wọn là, nitori Jesu dá awọn ti o n gbé ibẹ̀ lẹbi nigba ti O dá awọn ilu naa lẹbi. A o pa awọn eniyan naa run, ki i ṣe ilu nikan. O wi pe ni ọjọ idajọ, yoo sàn fun awọn ara Sidoni ati Tire, awọn ilu igba ni, ti awọn wolii ti sọrọ ibawi sí, jù fun awọn ara ilu wọnyii lọ.

### Idajọ

Sidoni ati Tire jẹ ilu olokiki nitori owò ṣiṣe ati ọrọ̀ wọn, ṣugbọn ẹ̀ṣẹ mú idajọ Ọlọrun wá sori wọn, wọn si sọ ògo wọn nù.

Ki i ṣe pe wọn sọ ọrọ̀ ati agbara wọn ninu ayé nù nikan, ṣugbọn iwe itan sọ fun wa pe awọn ilu wọnyii di ijẹ lọwọ awọn ọta wọn to bẹẹ ti wọn ko ti i gba ọrọ̀ wọn pada titi di oni.

Bayii ni wọn jiya pupọ fun ẹ̀ṣẹ wọn, ṣugbọn wọn kò ti i gba idajọ ikẹyin: "Mo si ri itẹ̀ funfun nla kan, ati ẹni ti o joko lori rẹ̀…. Mo si ri awọn okú, ati ewe ati àgba, nwọn duro niwaju itẹ; a si ṣi awọn iwe silẹ;…. a si ṣe idajọ fun awọn okú lati inu ohun ti a ti kọ sinu awọn iwe na, gẹgẹ bi iṣẹ wọn" (Ifihan 20:11-15).

Bi awọn ara Sidoni ati Tire ti buru to yii, Jesu wi pe wọn i bá ti ronupiwada, bi o ba ṣe pe wọ́n ri iṣẹ agbara ti Jesu ṣe ni Korasini ati Bẹtsaida. Wọn i ba ti ronupiwada ninu aṣọ ọ̀fọ̀ ati eérú. A lo ọrọ wọnyii niye igbà ninu Bibeli. Nigba pupọ ni o jẹ́ ami ti ode ara ti o n fi ironupiwada ti o jinlẹ ati kikọ ẹ̀ṣẹ silẹ hàn. Lonii nipa ẹkún kikoro ati ibanujẹ ẹni iwa-bi-Ọlọrun ni a fi maa n ronupiwada. Ironupiwada ni jijẹwọ ẹ̀ṣẹ wa ati kikọ ẹyin si wọn. Ohunkohun ti o ba ti yatọ si eyi ki i ṣe ironupiwada tootọ.

### Imọlẹ tabi Okunkun

Jesu ti fi Kapernaumu ṣe ile Rẹ̀. A kà ninu Matteu ori kẹrin pe Jesu fi Nasarẹti silẹ, O si n gbé ni Kapernaumu lati mu asọtẹlẹ ni ṣẹ pe, "Awọn ti o joko ninu òkunkun ri imọlẹ nlá." Jesu fun awọn eniyan naa ni anfaani lati ri igbala. O ṣe ọpọlọpọ iṣẹ iyanu, O waasu Ọrọ naa, O si kilọ fun wọn, ṣugbọn wọn yan ọna ara wọn ti o lọ sinu iparun. Wọn i ba ti gba imọlẹ naa ṣugbọn wọn fẹ òkunkun ju imọlẹ lọ.

Kapernaumu ni ọrọ̀ pupọ, ati anfaani ti o tobi ju lọ; ṣugbọn o ṣe ni laanu pe iparun nlánlà n duro de e! Jesu wi pe, Sodomu i ba wà sibẹ bi o ba ṣe pe o ti ni iru anfaani ti Kapernaumu ni. Sodomu ni ilu buburu ni ti Lọti gbé – ilu ti a fi iná ati sulfuru lati ọdọ Ọlọrun parun nitori ẹ̀ṣẹ wọn ti o papọju.

Ninu Juda, a kà pe a fi awọn eniyan Sodomu lelẹ bi apẹẹrẹ jijẹ iyà iná ainipẹkun. Bi yoo ba sàn fun Sodomu ju Kapernaumu lọ ni ọjọ idajọ, bawo ni yoo ti buru to fun Kapernaumu nigba naa!

### Oluṣe ki i ṣe Olugbọ Nikan

Gẹgẹ bi a ti fi Sodomu lelẹ fun apẹẹrẹ, bakan naa ni awọn ilu wọnyii jẹ́ ikilọ fun wa. Ọpọ eniyan ni wọn maan jokoo ninu isin, wọn n gba imọlẹ lati inu Ọrọ Ọlọrun, wọn n gbọ́ ẹri, wọn si n ka iwe Ihinrere, ṣugbọn sibẹ wọn n rin ninu òkunkun. "Eyi ni idajọ na pe, imọlẹ wá si aiye, awọn enia si fẹ òkunkun jù imọlẹ lọ, nitoriti iṣẹ wọn buru" (Johannu 3:19).

Ọpọlọpọ eniyan ni wọn n gbọ́ Ọrọ Ọlọrun ṣugbọn ti wọn ki i ṣe e. Awọn miiran "a mã fi" ọjọ igbala wọn dọla. Awọn miiran n gbiyanju lati dá ara wọn lare, wọn a si maa rò pe awọn "ko ti i buru jù." Ki i ṣe ohun ti awa rò pe o tọnà ni a o fi dá wa lẹjọ, bi ko ṣe nipa Ọrọ Ọlọrun. "Ẹniti nṣe idajọ mi li Oluwa" (1 Kọrinti 4:4). O le jẹ pe awọn ohun ti wọn kò naani tabi ti wọn kuna lati ṣe ni yoo dí wọn lọwọ lati wọ Ọrun. "Bikoṣepe ẹnyin ba pada, ki ẹ si dabi awọn ọmọ kekere, ẹnyin kì yio le wọle ijọba ọrun" (Matteu 18:3). "Ki iwọ ki o fi gbogbo àiya rẹ, ati gbogbo ọkàn rẹ, ati gbogbo inu rẹ, fẹ́ Ọlọrun Oluwa rẹ" (Matteu 22:37). "Ẹ tò iṣura jọ fun ara nyin li ọrun" (Matteu 6:20). "Ẹ tète mã wá ijọba Ọlọrun na, ati ododo rẹ̀" (Matteu 6:33). Diẹ ninu awọn aṣẹ ti a fi fun ni ninu Bibeli ni wọnyii. Bi ẹnikẹni ba kuna lati ṣe awọn nnkan wọnyii, oun ko le reti lati gbadun ibukun awọn ọmọ Ọlọrun. Awọn ẹlomiran le rò pe Ọlọrun yoo dẹlẹkẹ (gbà bẹẹ bẹẹ) fun wọn, ṣugbọn kò si ibi kan ninu Ọrọ Ọlọrun ti o fi idi eyi mulẹ̀. "Ọlọrun ki iṣe ojusaju enia" (Iṣe Awọn Apọsteli 10:34).

Ohun ti o lewu ni lati ri imọlẹ Ihinrere, ki a si kọ̀ lati rin ninu rẹ. A fi ẹkọ yii fun ni lati fi ojuṣe eniyan si Ọlọrun hàn án nipa ipe Ihinrere. O wà fun Onigbagbọ gẹgẹ bi o ti wá fun ẹlẹṣẹ, nitori ki i ṣe nipa ti ara wa nikan ni a oo jihin, ṣugbọn nipa ti awọn ẹlomiran pẹlu. Ninu Iwaasu lori Oke Jesu wi pe, "Ẹnyin ni imọlẹ aiye" ati pe, "Ẹ jẹ ki imọlẹ nyin ki o mọlẹ tobẽ niwaju enia, ki nwọn ki o le mã ri iṣẹ rere nyin, ki wọn ki o le ma yin Baba nyin ti mbẹ li ọrun logo."

Olukuluku ọmọ Ọlọrun ni o gbọdọ rin ninu imọlẹ gẹgẹ bi a ti fi fun un. Bi o ba ti n gba imọlẹ si i, bẹẹ ni o n rin ninu rẹ, bẹẹ ni o si n dagba si i nipa ti ẹmi, gẹgẹ bi ọmọ-ọwọ ti maa n dagba nipa ti ara. Ọmọ-ọwọ le ri wara, ki o gbe e lọwọ, ki o si maa gbe e kiri paapaa, ṣugbọn bikoṣe pe o ba mu un, ki ounjẹ naa si dà ninu rẹ̀, wara yii ko ni le ṣe e ni ire kan. Ṣugbọn bi ọmọ-ọwọ ti maa n mu wara ti o si n di ara fun un ni yoo maa dagba, nikẹyin ọmọ-ọwọ naa a si le jẹ awọn ounjẹ miiran pẹlu. Bayii ni o ri pẹlu ọmọ-ọwọ ninu Kristi bi o ba ti n gbọ́ Ọrọ Ọlọrun, ti o si n gba a ti o si n mu awọn ẹkọ wọnyii lò ninu igbesi-ayé rẹ̀, bẹẹ ni yoo maa dagba ninu ẹmi titi oun yoo fi wulo si i fun Ihinrere. Ọlọrun yoo maa kọ́ awọn ọmọ Rẹ̀, yoo si maa fi awọn ileri iyebiye ti o wà ninu Bibeli hàn wọ́n; Oun yoo maa fun wọn ni òye Ọrọ naa, eyi ti o n rú awọn ọjọgbọn ayé loju.

**Ipè**

Bi Jesu ti ṣe awọn ikilọ wọnyii tán, O fun gbogbo ayé ni ipè bayii pé, "Ẹ wá sọdọ mi," Ipè yii ti wà, o si tun wà sibẹ fun "ẹnikẹni ti o bá fẹ." Ipè Rẹ̀ yatọ si ti ayé, eyi ti kò wà fun gbogbo eniyan. Ki ẹnikẹni to le dara pọ̀ mọ́ ẹgbẹ ọmọ-ogun orilẹ-ede wa, ọdọmọkunrin naa gbọdọ pé iye ọdun kan, ki o si ga dé àye kan. Awọn ile-iwe miiran maa n fẹ ki awọn ọmọ ile-iwe ti dé àye kan ninu ẹkọ wọn, ki a to le gbà wọn. Ọpọlọpọ igba ni o jẹ pe awọn nnkan bi ilera, ibilẹ, giga, owó, ẹ̀kọ́, ẹbùn, ọgbọn, iṣẹ́, imọ̀ ati awọn nnkan miiran ni o maa n fi hàn bi ẹnikẹni yoo le dara pọ̀ mọ́ ẹgbẹ́ kan tabi bẹẹ kọ́. Ṣugbọn kò si ọ̀kan ninu awọn nnkan wọnyii ti o ṣe pataki nigba ti ẹnikẹni ba di ẹya ara Kristi.

Ninu ayé yii, ki i ṣe gbogbo eniyan ni o n ṣiṣẹ, ṣugbọn ọrọ yii n sọ nipa awọn nnkan ti ẹmi. Awọn ti kò i ti ri igbala n ṣe iṣẹ labẹ ẹrù ẹ̀ṣẹ̀, ṣugbọn alaafia ati isinmi wà fun ọkàn ti a dá lare nipa aṣẹ Kristi.

Jesu wi pe, "Gbà àjaga mi si ọrun nyin." A le pe àjaga ni ijanu. On ni ohun ti o so ẹranko meji pọ̀ mọ́ ara wọn; ṣugbọn nihin yii, a o so Onigbagbọ́ pọ̀ mọ́ Jesu. Ajaga yii jẹ́ ami isin. O fi hàn pe ki i ṣe ẹrú awọn ohun ayé yii, ṣugbọn iranṣẹ Kristi ni. A ti so o pọ mọ Kristi, o si n ṣiṣẹ fun Un. A sọ fun ni pe ajaga maa n mu ki o rọrun lati fà tabi lati ru ẹrù nla. Bi ẹni meji ba duro ni ẹgbẹkẹgbẹ, a o fi ajaga naa si ejika wọn, awọn mejeeji yoo si jumọ gbé ẹrù naa. Boya iwọ ti gbiyanju lati fi apá gbé ẹru kan, lai pẹ iwọ yoo ri pe ọwọ bẹrẹ si ro ọ́, iwọ yoo si gbé e silẹ. Ṣugbọn nigba ti a ba gbe ẹru kan naa lé ọ lori, yoo rọrun fun ọ lati rù u. Tabi boya o ti gbiyanju lati fa kẹkẹ ti ẹrù wuwo wà lori rẹ̀, ṣugbọn kò ṣe e ṣe. Ṣugbọn fi okun so kẹkẹ naa mọ́ ejika ati àya rẹ. Bi iwọ ba sinmi le okun yii, o daju pe iwọ yoo fa ẹru ti o wuwo ju eyi ti o le fi ọwọ fà lọ. Bakan naa ni Jesu maa n fun Onigbagbọ ni ajaga lati mu ẹru rẹ̀ fuyẹ. Oun yoo ri pe, ki i ṣe pe Kristi n ru eyi ti o wuwo ju nikan, ṣugbọn O mu ajaga Rẹ̀ rọrun, O si mu ẹru Rẹ̀ fuyẹ.

**AWỌN IBEERE**

1. Ki ni ṣe ti Jesu bá awọn ilu wọnyii wí?
2. Darukọ awọn eniyan diẹ ninu Bibeli ti wọn ronupiwada ninu aṣọ ọfọ ati eeru.
3. Ki ni ṣe ti Ọlọrun pa Sodomu run? Bawo ni O ṣe pa a run?
4. Awọn wo ni ọmọ-ọwọ ninu Kristi? Bawo ni wọn ṣe n dagba?
5. Ọkunrin wo ni o jẹ apẹẹrẹ iwa tutù ninu Majẹmu Laelae?
6. Bawo ni eniyan ṣe le ni isinmi fun ọkàn rẹ̀?